# IṢẸ IRIJU WA

**1 Kọrinti 4:1-21; 9:16-27; 2 Kọrinti 5:17-21; 6:1-10**

**ẸKỌ 391 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "A mbere lọwọ iriju pe ki oluwarẹ̀ na ki o jẹ olõtọ" (1 Kọrinti 4:2).**

**I Iṣẹ Iriju**

1 A n beere lọwọ awọn iriju ki wọn jẹ oloootọ nitori wọn yoo jihin fun Ọlọrun, 1 Kọrinti 4:1-5; Luku 12:41-48; Romu 14:12; 1 Tẹssalonika 2:4; Titu 1:7-9; Heberu 13:17

2 Awọn iriju ni lati fi irẹlẹ jẹ́ ipe wọn ohunkohun ti o wu ki de ba wọn ninu igbesi-ayé wọn, 1 Kọrinti 4:6-21; Johannu 16:33; Romu 12:3; 1 Peteru 4:10

3 Lati ọdọ Ọlọrun wa ni ipe iṣẹ iriju, bi a ba si fi tifẹtifẹ ọkàn jẹ ipe naa, yoo mu ere ayeraye wa, 1 Kọrinti 9:16-27; 1 Peteru 5:2

**II Jijẹ Ikọ̀**

1 Ikọ̀ fun Kristi ni lati kọ́ "mu ninu eso wọnni" ani o ni lati di ẹda titun ninu Kristi, 2 Kọrinti 5:17-20; Efesu 6:20; 2 Timoteu 2:6

2 Kristi jiya nitori awọn ẹṣẹ wa, 2 Kọrinti 5:21; Isaiah 53:5; Heberu 2:9; 1 Peteru 2:24; 3:18

3 Awọn ikọ̀ fun Kristi ni lati jẹ ẹni ti n jere ọkàn, 2 Kọrinti 6:1, 2; Iṣe Awọn Apọsteli 26:16-18; Daniẹli 12:3; Matteu 4:19

4 Awọn ikọ̀ ni lati gbé igbesi-ayé ailẹgan bi o ba tilẹ ṣe pe wọn wa labẹ idanwo kikoro, 2 Kọrinti 6:3-10; 4:1, 2, 8-11; Filippi 2:15; 1 Timoteu 3:2-4

**ALAYE**

**Ohun Ijinlẹ ti Ihinrere**

Paulu Apọsteli sọ fun Timoteu pe, "Titobi ni ohun ijinlẹ iwa-bi-Ọlọrun, ẹniti a fihan ninu ara, ti a dalare ninu Ẹmi, ti awọn angẹli ri, ti a waasu rẹ̀ larin awọn orilẹ-ede, ti a gbagbọ ninu aiye ti a gba soke sinu ogo" (1 Timoteu 3:16). Wọnyii jẹ́ ọrọ ijinlẹ tootọ; lati ayebaye ni ọrọ ijinleẹ yii si ti n daamu awọn ọjọgbọn ti o ga ju lọ ninu ayé. Ṣugbọn awọn otitọ ijinlẹ wọnyi ko gbọdọ jẹ ohun ti o fara sin fun ọkan oloootọ. Jesu wi fun awọn ọmọ ẹyin Rẹ̀ pe, "Ẹnyin li a fifun lati mọ̀ ohun ijinlẹ ijọba ọrun, ṣugbọn awọn (alaigbagbọ) li a kò fifun" (Matteu 13:11).

Paulu ṣe alaye ijinlẹ yii fun awọn ara Kolosse pe, "Ami ohun ijinlẹ ti o ti farasin lati aiyeraiye ati lati irandiran, ṣugbọn ti a ti fihàn nisisiyi fun awọn enia mimọ́ rẹ̀; awọn ẹniti Ọlọrun fẹ lati fi ọrọ̀ ohun ijinlẹ yi larin awọn Keferi hàn fun, ti iṣe Kristi ninu nyin, ireti ogo" (Kolosse 1:26, 27). Nini Kristi ninu ọkàn ẹni, lati di ẹbi Ọlọrun, ati lati di ẹda titun ninu Kristi Jesu, jẹ́ ohun ijinlẹ tootọ loju awọn alaigbagbọ́. Fun awọn ti o gbagbọ́, iriri ti ẹmi yii ni o mu iyipada bá igbesi ayé wọn, ti o si n mu iyipada ayeraye bá ibugbe ọkàn wọn.

**Iṣẹ Iriju ti Ihinrere**

Niwọn bi agbara iyanu Ihinrere Kristi ti o n ṣe iyipada ninu ọkàn ba le mu iriri ti o jinlẹ bayii wá, ki ni yoo ha jẹ ojuṣe ẹni ti a pe lati jẹ Iranṣẹ Ihinrere naa, ani gẹgẹ bi ori ẹkọ wa ti wi, "Iriju awọn ohun ijinlẹ Ọlọrun?" Ko si ipe ti o ga ju eyi lọ, bẹẹ ni ko si iṣẹ kan ti o ni èrè lori ju u lọ, ko si si ojuṣe ti o pọ ju ki a jẹ iranṣẹ ninu Ihinrere Jesu Kristi. Njẹ bi ipe naa ba ṣe pataki to bayii, o ha le ya ni lẹnu eredi rẹ̀ ti Paulu fi wi pe a n beere lọwọ iriju pe ki oluwarẹ naa ki o jẹ́ oloootọ? Igbala tabi iparun ọkàn ẹda duro le ijolootọ iriju lati kede otitọ naa pẹlu ifororoyan ati imisi Ẹmi Mimọ́, ijolootọ rẹ̀ ni gbigbe igbesi-ayé mimọ ti Onigbagbọ́ lojoojumọ. Iṣẹ rẹ̀ ki i ṣe lati sọ fun awọn eniyan nipa Jesu ati agbara Rẹ̀ lati gbala nikan, ṣugbọn oun paapaa ni lati jẹ apẹẹrẹ aaye iṣẹ oore-ọfẹ ti o wà ninu Ihinrere Jesu Kristi ti o n sọ ayé eniyan di ọtun. (Ka Romu 10:14).

Iṣẹ iriju yii ki i ṣe eyi ti a n gba wa si nitori pe a ni imọ ẹkọ giga tabi nitori pe a ni oyè ẹkọ giga bi ko ṣe ipe imọ ani lati ọdọ Ọlọrun. Ojiṣẹ Ihinrere Ọlọrun tootọ jẹ ẹni ti o duro laaarin alaaye ati oku gẹgẹ bi aṣoju Ọlọrun ayeraye, aiku, oloootọ, alaanu ati Ọlọrun ti ifẹ Rẹ̀ ki i ṣá. Iṣẹ rẹ̀ ni lati mu awọn eniyan mọ Kristi; ani bi o ba tilẹ dabi ẹni pe oun jẹ ohùn kan ṣoṣo ti n kigbe ni aginju ti a ko si ka a si. Oun gbọdọ ṣe itọni, o gbọdọ ba ni wi, o si gbọdọ gba ni niyanju pẹlu gbogbo ipamọra ati ẹkọ. Ki eyi to le ṣe e ṣe, alufaa naa ni lati "kọ́ mu ninu eso wọnni," eyi si gbọdọ hàn ninu iṣọwọsi-

huwa rẹ̀, nipa gbigbe igbesi-aye iwa mimọ ati iwa-bi-Ọlọrun rẹ̀, igbesi-aye adura rẹ̀, ati ẹmi aimọtara-ẹni-nikan ninu iṣẹ-isin rẹ̀ si Ọlọrun ati eniyan.

**Iṣiro Iṣẹ Iriju**

Nitori pe lati ọdọ Ọlọrun wa ni ipe si iṣẹ iriju, Ọlọrun gan an ni alufaa yoo jihin iṣẹ rẹ̀ fun. Paulu wi pe, "Ẹniti nṣe idajọ mi li Oluwa." Ṣugbọn eyi ko fun alufaa ijọ ni anfanni lati maa jẹ gaba lori ini Ọlọrun tabi lati jẹ aninilara. Awọn alufaa ni lati maa rin ni irẹlẹ pẹlu Ọlọrun – eyi gbọdọ ri bẹẹ -- nitori pe awọn ni iriju ohun ijinlẹ Ọlọrun, Ọlọrun yoo si beere lọwọ wọn bi wọn ti ṣe lo ipo wọn si.

Paulu tun fi ye ni pe ipo alufaa ninu Ihinrere jẹ eyi ti o fara hàn kedere. O wi bayii pe, "Nitori mo rò pe Ọlọrun ti yan awa Apọsteli kẹhin bi awọn ẹniti a dalẹbi ikú: nitoriti a fi wa ṣe iran wo fun aiye, ati fun angẹli, ati fun enia. Awa jẹ aṣiwere nitori Kristi." Nitori pe wọn waasu ohun ijinlẹ yii, nigba pupọ ni a o ṣì wọn gbọ́, ti a o si yi ọrọ wọn po, eyi a si mu ki a ṣe inunibini pupọ si wọn; ṣugbọn eyi ko gbọdọ fò wọn laya. Wọn ni lati di otitọ mu ki wọǹ si rin ni irẹlẹ pẹlu Ọlọrun wọn.

Ohun ti a sọ nihin nipa awọn alufaa ninu Ihinrere gẹgẹ bi iriju jẹ ohun ti a le sọ pẹlu nipa awọn Onigbagbọ́. Olukuluku Onigbagbọ́ ni o ni awọn ẹbun ati ipe pataki ti Ọlọrun n beere lọwọ rẹ̀ pe ki o jẹ olooototọ si. "Ailabamọ li ẹ̀bun ati ipe Ọlọrun."

Jesu pa owe nipa fifi talẹnti fun awọn ọmọ-ọdọ Rẹ̀: "O si fi talẹnti marun fun ọkan, o fi meji fun ẹni keji, ati ọkan fun ẹni kẹta o fi fun olukuluku gẹgẹ bi agbara rẹ̀ ti ri." Oluwa mọ agbara olukuluku eniyan, ki yoo si beere lọwọ ẹnikẹni ju eyi ti o lagbara lati ṣe lọ. Meji ninu awọn iranṣẹ wọnyii fi tọkantọkan ṣe ojuṣe wọn, wọn si jere ilọpo talẹnti wọn si i; nigba ti Oluwa si pada de lati ba wọn ṣiro, ọrọ iṣiri ti o tayọ ti wọn ri gba ni pe, wọn ti ṣe olooototọ. Ọmọ-ọdọ kan kuna lati fi talẹnti ti rẹ̀ jere, nitori ti o ri i mọlẹ. Ni tootọ o dá talẹnti ti a fi fun un pada; o tọju rẹ̀ daradara, ṣugbọn ko fi ṣiṣẹ lati mu un dagba soke tabi lati jẹ ki o le si i. Abayọrisi rẹ ni pe, a gba talẹnti kan ṣoṣo naa lọwọ rẹ̀, a si gbe oun paapaa sọ sinu okunkun nibi ti ẹkun ati ipahinkeke gbe wa (Matteu 26:14-30).

O jẹ ọranyan pe Onigbagbọ gbọdọ ṣiṣẹ fun Oluwa: A paa laṣẹ fun un ni. "Ki iṣe ẹnyin li o yàn mi, ṣugbọn emi li o yàn nyin, mo si fi nyin sipo, ki ẹnyin ki o le lọ, ki ẹ si so eso, ati ki eso nyin le duro."

Jesu ni ẹni ti o ga ju lọ ninu gbogbo awọn iriju, Oun si ni apẹẹrẹ ti o tayọ. Oun ni olori awọn Oluṣọ-Agutan. Oun ko wa lati kọ́ ilẹ-ọba ti ara Rẹ̀, ṣugbọn O tẹri ara Rẹ̀ ba buruburu fun Baba Rẹ̀ ti ó wà ni Ọrun. O wi pe, Oun ko wa lati ṣe ifẹ ti ara Oun bi ko ṣe ifẹ ti Ẹni ti O rán Oun. Itara ọkan Rẹ̀ ni alaafia awọn eniyan ti a ran An lati ṣe iranṣẹ fún. O wo awọn alaisan sàn. O ṣe awotan awọn ọkan onirobinujẹ; O fẹ awọn ẹlẹṣẹ, O si dá awọn igbekun silẹ. O tan imọlẹ si awọn ti o wà ninu okunkun, ati ni opin rẹ̀, O fi ẹmi Rẹ̀ lẹlẹ fun awọn agutan Rẹ̀.

**Ikọ̀ fun Kristi**

Itumọ ikọ̀ ninu iwe atumọ ede ni: "Iranṣẹ ti o ga ju lọ ti a fi si ilẹ ijọba ajeji gẹgẹ bi aṣoju ijọba ilu ti oun tikara rẹ̀." Ipo ikọ̀ ni àye ti o ti o ga ju lo ni ilẹ ijọba ilu miiran ti a le fi ọmọ-ibilẹ ilu kan si; dajudaju oun ni oniṣẹ ijọba ti o ga ju lọ fun ilu rẹ̀. Bakan naa ni olukuluku Onigbagbọ́ jẹ. "Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i nwọn si di titun." O di ẹda titun. O di ọmọ ibilẹ ilu titun. Ọrun ni ile rẹ̀. Arin-irin-ajo ni nigba ti o wà ninu ayé nihin, aṣoju ilu-ibilẹ rẹ̀ tootọ, ti i ṣe Ọrun.

**Iṣẹ Ikọ̀**

Ki eniyan to le jẹ ikọ fun Kristi, o gbọdọ kọkọ ba Ọlọrun laja nipa Jesu Kristi, ẹni ti a mu pada bọ̀ sinu ojurere ati irẹpọ pẹlu Ọlọrun eyi ti ẹ̀ṣẹ ti mu wa sọnu. Nitori ti ikọ̀ fun Kristi ti di ẹda titun ati pe ilu ibilẹ rẹ̀ wa ni Ọrun, gbogbo ironu rẹ̀ wa lori awọn nnkan ti ó wà loke; ṣugbọn nigba ti o ba wà ninu aye nihin, ikọ̀ tootọ a maa ni iwuwo-ọkan fun awọn ọkàn wọnni ti o n ṣegbe ninu ẹ̀ṣẹ, gẹgẹ bi oun paapaa ti jẹ lẹẹkan ri. Iṣẹ ikọ̀ yii ko mọ nikan si ati jẹ iriju rere fun ilu rẹ̀ ṣugbọn lati jẹ alabaṣiṣẹpọ̀ pẹlu Kristi ni jijere ọkàn fun Ijọba Ọrun. Oun, gẹgẹ bi ikọ̀ n ṣoju fun Ọlọrun, o si n bẹ awọn eniyan ki wọn ba Ọlọrun laja.

Paulu Apọsteli, gẹgẹ bi apẹẹrẹ ikọ̀ rere, sọ eredi pataki fun ilaja. O si pe Kristi ti ko mọ ẹṣẹkẹṣẹ ri, a fi I ṣe ẹ̀ṣẹ nitori wa, ki awa le di ododo Ọlọrun ninu Rẹ̀. Jesu Kristi tikara Rẹ̀ di Ọdọ-gutan Irubọ. Oun di arọpo fun wa. O jiya, O si ku iku oro lori igi agbelebu ni Kalfari, ki i ṣe fun ẹ̀ṣẹ ara Rẹ̀ -- nitori O jẹ Ọmọ Ọlọrun ti ko lẹṣẹ -- Ṣugbọn O gbé ẹ̀ṣẹ awa ru, O si san gbese iyà naa ni kikun.

Paulu Apọsteli si tun sọ akoko ti o yẹ ki ẹlẹṣẹ ki o yipada si Olugbala Onifẹ yii; nisisiyii ni, nitori “nisisiyi ni akoko itẹwọgba; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbala.” O mọ daju pe ko si ileri fun ọjọ ọla.

Kò si ipe ti o ga ju pe ki a lo iba ọdun diẹ ti a ni ninu ayé yii gẹgẹ bi ikọ̀ tootọ fun Ọlọrun. Ki lo le jẹ akitiyan ti o lọla ju pe ki a maa ṣiṣẹ lati jere awọn ọkan kuro lọna ọrun apaadi ati lati tọ wọn sọna iwa mimọ ti o lọ taara si Ọrun? A, iba ti dara to bi ọpọ eniyan ba ke hẹ ipe ti o ga ju gbogbo ipe lọ yii! Jesu wi pe: “Lõtọ ni ikorè pọ̀, ṣugbọn awọn alagbaṣe ko to nkan; nitorina ẹ gbadura si Oluwa ikorè ki o le ran awọn alagbaṣe sinu ikorè rẹ̀” (Matteu 9:37, 38).

**AWỌN IBEERE**

1 Lọna wo ni Onigbagbọ fi jẹ́ iriju Ọlọrun?

2 Ki ni ṣe ti a ṣe n beere lọwọ iriju pe ki o jẹ oloootọ?

3 Ta ni awọn iriju yoo ṣe iṣiro fun?

4 Sọ diẹ ninu awọn talẹnti ti Oluwa le lo ninu iṣẹ iriju wa.

5 Ki ni Paulu n wi nihin nigba ti o wi pe oun di ohun gbogbo fun gbogbo eniyan?

6 Sọ itumọ Onigbagbọ gẹgẹ bi a ti ṣe alaye rẹ̀ ninu ori-ẹkọ wa.

7 Ṣe alaye bi a ṣe fi Onigbagbọ́ wé ikọ̀.

8 Ọna wo ni ẹlẹṣẹ le gba bá Ọlọrun laja?

9 Akoko wo ni o tọ́ lati wa igbala?